
NÍSISÌYÍ TÍ
O TI DI
ÀTÚNBÍ
Chris Oyakhilome


NÍSISÌYÍ TÍ
O ṬI DI
ÀTÚNBÍ
Chris Oyakhilome

Gbogbo ẹsẹ Bíbélì tí a lò nínú òwe yìí jẹ́ ti KJGB bíbẹ̀kọ́ bẹ́ẹ̀ ka fihàn.
Títẹ̀sita ẹkẹrin irú rẹ̀ 2009
ISBN 978–34658-7-2
Àtẹ̀jáde láti: ilé iṣẹ́ ìtẹ̀wé tí LogbeWorld
Àṣẹ kíkọ © 2006

Published by: LoveWorld Publishing
3, Adebayo Akande Street, Oregun, Ikeja, Lagos, Nigeria.
Email: info@loveworldbooks.org
Website: www.loveworldbooks.org

Gbogbo ẹ̀tọ̀ títẹ̀síta lábẹ́ òfin ti ìlú òkèèrè. Àwọn akoonu tàbí ìdáàbòbò rẹ kò gbọ́ dọ̀ jẹ́ ati ntẹ ni odidi tàbí apákan ní ọ̀nàkọnà láì si àkọsílẹ̀ fún ìgbàlaaye láti ilé-iṣẹ́ ìtẹ̀wé síta ti LogbeWorld.

# Àwọn Àkòónú


1. Ìwo gangan 7
2. O jẹ́ ẹ̀dá titun 11
3. O ni ìṣẹ́dá àti ìyè Ọlọ́run 13
4. O jẹ́ òdodo ti Ọlọ́run 17
5. Adà ọ láre 19
6. A yà ọ́ sí mímọ́! 21
7. A ti gbà ọ́? 23
8. Ẹ̀mí Ọlọ́run □ gbé inú rẹ! 25
9. Kínni wàá ṣe nígbà tí èrò àìtọ́ bá wá sínú ọkàn rẹ 27
10. Kínni wàá ṣe nígbàtí ọ̀rẹ̀ àtijọ ba n gbìyànjú láti ko ìrẹ̀wẹ̀sì bá ọ? 35
11. Kínni wàá ṣe nígbà tí inúbinbíni àti ìpọnjú bá dé? 41
12. Ìwọ àti Ẹ̀mí Mímọ́ 47
13. Njẹ́ o gbọdọ̀ lọ si ilé ọ̀jọ́sìn/ṣọ́ọ̀sì 57

# Olùfẹ́ Ọ̀wọ́n

Kú orí ire ti ìgbàlà ọ̀fẹ́ ti ayérayé èyí ti o rí gbà nígbà tí o gba Jesu Kristi gẹ́gẹ́ bí Olùwa àti Olùgbàlà rẹ̀.

Mo fẹ́ pín àwọn òtítọ́ yìí pẹ̀lú rẹ, èyí ti o jẹ́ ìpilẹ̀ṣẹ̀ si ìgbàgbọ́ ti kristiani, òtítọ́ èyí ti o le mọ ìgbé ayé ti o dúró tí o si dára nínú Kristi le lórí . Fi ara balẹ̀ ka ohun èlò yìí yóò fi ìkòré ayérayé fún ọ. Mo gbàdúrà pé Ọlọ́run yóò fún ọ ni ẹ̀mí  ọgbọ́n àti ìfihàn ìmọ̀ rẹ̀, ti yóò si ojú òye rẹ láti mọ títóbí ìrètí ìpè ti o pe ọ àti kí o lè mọ̀ ohun gbogbo ti a ti fifun ọ nínú Kristi, amin.

Ohun èlò yìí yóò ràn ọ lọ́wọ́ láti bẹ̀rẹ̀ ìgbé ayé ayé titun nínú Kristi jesu. Bi o ti n ka, máa wọ inú Bíbélì ki o si máa ṣe àṣàrò nínú ìwé mímọ́ fún ra ara rẹ̀. Mo gbàgbọ́ pe iṣẹ́ ìránṣẹ́

ti o wa nínú rẹ yóò yìí ayé rẹ padà àti ràn ọ́ lọ́wọ́ láti sètò ọjọ́ ọ̀la rẹ gẹ́gẹ́ bí òfin inú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ti wi. Ki Ọlọ́run kò bùkún ọ lọ́pọ̀lọpọ̀ ni orúkọ Jesu, àmin.

Olùṣọ́-Àgùtàn *Chris. Oyakhilome.*

# 1

# ÌWỌ GANGAN

Oju ara tí o n ri yìí lọ. O ju àgọ́ ara/kòrofo èyí tí gbogbo ẹ̀yà ara rẹ ń gbé inú rẹ lọ Óojú, etí, ọwọ́, ẹnu imúÒ. Ni inú rẹ, ohunkan gaan wa níbẹ̀, ẹnikan ti o ju gbgbo ara rẹ lọ. Ohun ni Ẹ̀mí ènìyàn rẹ, ohun gan an ni ìwọ.

Ẹniti inú ya òun ni bíbélì n tọ́ka sí nínú **I Peteru 3:4:** "ṣùgbọ́n kí ó jẹ́ ti ẹnití o farasin li ọkàn, nínú ọ̀sọ àìdibàjẹ́ ti ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀ àti ẹ̀mí tútù". Nígbàtí ara ènìyàn ba kú. Ẹ̀mí rẹ si wa

láyé. O si tún jẹ́ ènìyàn tí ó jẹ́ tẹ́lẹ̀ ki o tó kú, kò sọ ohun ohunkóhun kankan nù, jù wípé o ni sọ agbára láti le ṣe iṣẹ́ ọ̀rọ̀ nínú ayé lọ. Ara rẹ ti le ku, ṣùgbọ́n ìwọ gangan bi ènìyàn, Èmí ènìyàn si ni gbogbo ìmọ̀ohun tí o ni kí o tó kú.

Jesu sọ ìtànkan nínú Luku 16 nípa àwọn ọkùnrin méjì tí wọ́n kú. Ọkan jẹ́ alágbe ti orúkọ rẹ ń jẹ́ Lasaru. Kì í ṣe pe nítorí tí ó jẹ́ alágbe, ṣùgbọ́n lótítọ́ o jẹ́ tálákà, o ni ọkàn tí ó tọ́. Nígbà tí o kú a gbe lọ si okan aya Abrahamu. Arákùnrin kéjì na kú. Arakùnrin náà jẹ́ ọlọ́rọ̀ nínú aye. Ṣùgbọ́n kò gbé ìgbé aye òdodo.

Sàkíyèsí pé nígbàtí o kú, a sin òkú rẹ̀ sínú ilé, ṣùgbọ́n Jesu sọ wípé nínú ipò òkú ni o gbé ojú rẹ  sókè nínú iṣẹ́ oró, o si ri Lasaru ni ọkan-aya Abrahamu. O túmọ̀ si wípé ó sì tún le rí nǹkan o si ké, o wípé Baba Abrahamu, sàánú fún mi, ṣé o ri o tún le sọ̀rọ̀ Abrahamu dalohùn o si tún gbọ́ ohun Abrahamu, èyí ti ó jásí pe ó tún le gbọ́. Ọkùnrin ọlọ́rọ̀ náà sọ wípé

òrùngbẹ́ ń gbẹ òun, kíìṣe òrùngbẹ lásán ni o ń gbẹ, o tún joró nítorí náà o nbẹ̀bẹ̀ "Lasaru ki o tẹ̀ orika rẹ bọmi, kí o fi tù mi ni ahọ́n" kókó míràn tún nìyí o tún ni ìmọ̀oùn.

Gbogbo ẹ̀yà ara rẹ lópé síbẹ̀ kódà, o tún le rántí àwọn nǹkan nítorí o sọ wípé "njẹ́ mo bẹ̀ ọ́ "kí ìwọ ki o rán a lọ síilé láàrin àwọn òkú láti lọ wàásù fún àwọn arákùnrin rẹ̀". O ni àbúrò márùn ni ayé torínáà o lérò "Bóyá ti ẹnìkan láàrin àwọn òkú lè to wọn lọ, wọn yóò gbàgbọ́". O rántí àwọn arákùnrin rẹ̀. Èyí jẹ́ kí ó yé wa pe Ẹ̀mí ènìyàn si wa láàyé. Nígbàtí ènìyàn bá wa di àtúnbí, Ẹ̀mí ènìyàn rẹ ni àtúnbí:

**2 Korinti 5:17-18 (NKJV)** sọ wípé "Nítorí náà bi ẹnikẹ́ni bá wà nínú Kristi o di ẹ̀dá titun, ohun àtijọ ti kọjá lọ; kíyèsí wọn si di titun. Ohungbogbo si ti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run wá ẹniti o si ti ipasẹ̀ Jesu Kristi ba wa làjà sọ̀dọ̀ ara rẹ̀, ti o si ti fi iṣẹ́-ìránṣẹ́ ìlaja fún wa.

# 2

# O JẸ́ Ẹ̀DÁ TITUN

Nísisìyí ti o ti fi ayé rẹ fún Jesu Kristi láti jẹ́ Olúwa ayé rẹ, o ti yàtọ̀ si ohun ti o jẹ́ tẹ́lẹ̀ o lè máa yípadà ni òde ara rẹ, ṣùgbọ́n ni inú o ti di ẹni titun lápapọ̀. Nǹkan ti Bíbélì sọ nìyí, kìí ṣe wípé o dàbí ẹ̀dá titun, ṣùgbọ́n "ẹ̀dá titun ni o jẹ́ - ènìyàn titun tí kò ti wa tẹ́lẹ̀ ri **2 Korinti 5:17** kì í ṣe wípé a tún ọ ṣe. O jẹ́ ẹ̀dá titun - ènìyành titun lápapọ̀: Bákan náà, lótítọ́ ni pe ó jẹ́ ẹ̀dá titun inú, kò wa sọ wípé ara òde rẹ

yóò wa yàtọ̀. Tí o ba jẹ ẹniti o ń jẹ irun orí rẹ mọ́lẹ̀ kí ó tó di àtúnbí, bẹ́ẹ̀ náà ni yóò si wà, iṣẹ rẹ pẹ̀lú kò yàtọ̀ lèlíle àti àwọn alajọgbé rẹ kò yàtọ̀ kókó ibẹ̀ nípé, iye/iyì rẹ tìyàtọ̀ o ti ni àwọn iye ọ̀tun nítorí o ti di ènìyàn titun ní inú .

## 3

# O NI ÌṢẸ̀DÁ ÀTI ÌYÉ ỌLỌ́ RUN

Tí o bá tidi àtúnbí, Ọlọ́run ti fún ọ ni agbára láti di ọmọ rẹ̀ Johannu 1:12 ìyè

Ọlọ́run ti wọ inú ẹ̀mí ènìyàn rẹ. O wá ni ìyè titun, iye ti Ọlọ́run èyí ti Jesu ti mu ki o wà fún gbogbo ẹnikẹ́ni ti o ba gbààgbọ́. Irú àǹfààní wo niyí! O wa di alábapin nínú ìwà Ọlọ́run **2 Peteru 1:3-4.**

Ọlọ́run wa jẹ́ Baba nígbayí! Báwo? nipa ìbí ni a da ẹ̀dá ìdí si nìyí ti ajá ń fi n bi ajá.

**Johannu 1:12-13** sọ wípé ṣùgbọ́n iye àwọn ti o gbàá, àwọn ni o fi agbára fún láti di ọmọ Ọlọ́run, àni àwọn náà ti o gba orúkọ rẹ gbọ́. Àwọn ẹniti a bí, kìí ṣe nípa ti ẹ̀jẹ̀, tàbí nípa ti ìfẹ́ ara; bẹ́ẹ̀ ni kìí se nípa ìfẹ́ ènìyàn, bíkòse nípa ìfẹ́ ti Ọlọrùn".

Ọlọ́run ni ipa òbí sí ọ. O jẹ́ ara ilé rẹ nítorí náà ọmọ ìlú ọ̀run ni ibití o ń gbé Ọlọ́run jẹ́ onidúró fún ọ, yóò pèsè fún gbogbo àìní rẹ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ Ògo rẹ nínú Kristi Jesu **Filipi 4:19**. O ní ètò rere fún ayé rẹ, èyí tí o ti sètò ni ìsípòpadà ni kété tí o ti di àtúnbí. O jẹ́ ọmọ ti Ọlọ́run onifẹ́ fẹ́ràn, a si wa bi ọ sínú ìdílé onífẹ́. Èyí ṣe pàtàkì. O fún ọ ni ìyè titun yìí láti jẹ́ ọkan lára ọmọ ẹgbẹ́ ìjọba ọ̀run.

Bíbélì kéde rẹ wípé Ọlọ́run ti fún ọ ni ìyè ayérayé. Ìyè yìí ni o mbẹ nínú

Ọlọ́run. Èyí ti o jẹ́kí o ṣeéṣe fún mi láti jẹ́ ohun ti ó jẹ́. Èyí ni ìyè irú ti Ọlọ́run. Ìyè yìí ni kò jẹ́ kí o ṣeéṣe fún ibojì láti di jesu Kristi mu.

Èyí ni àjíndé ìyè, ìyè yìí si wa nínú rẹ.

Ẹrí náà si ni èyí pe Ọlọ́run fún wa ni ìyè àìnípẹ̀kun, ìyè yìí si mbẹ nínú ọmọ rẹ̀. Ẹniti o ba ni ọmọ, o ni ìyè ẹnití kò ba si ni ọmọ Ọlọ́run, kò ni ìyè. Nǹkan wọ̀nyìí ni mo kọ̀wé rẹ̀ si yin ani si ẹ̀yin ti o gbà orúkọ ọmọ Ọlọ́run gbọ́; ki ẹ̀yiìn kí ò lè mọ̀ pé ènyin ni ìyè àíníp ẹ̀kun, àní fún ẹyin ti ó gba orúkọ ọmọ Ọlọ́run gbọ́

**I Johannu 5:11-13.** Ẹniti o ba ni ọmọ ni o ni ìyè, nítorí ìyè yìí o wa nínú ọmọ

Ọlọ́run. Nígbàtí o ba gbàá, o gbà ìyè rẹ̀, a kò lè pa ọ run tàbí já ọ kúlẹ̀, nítorí Ẹ̀mí ẹniti o jí Jesu dìde kúrò nínú òkú ń gbé inú rẹ Romu 8:11.

**4**

# Ó JẸ́ ÒDODO ỌLỌ́RUN

2 Korinti 5:21 sọ wípé "Nítorí àti fii ṣe ẹsẹ̀ nítorí wa, ẹniti kò mọ ẹ̀ṣẹ̀kẹ́ṣẹ̀ rí, kí àwa le di òdodo Ọlọ́run nínú rẹ̀".

Fojú inú wo Ọlọ́run ti o ń ṣiṣẹ́ ohun ti a lè pè ni Àsopọ̀-ìṣẹ́dá o fi jesu ẹ̀ṣẹ̀ Óèyí ni ore-ọ̀fẹ́Ò fún wa, kí a wa ba le di òdodo Ọlọ́run nínú rẹ̀, Èyí ni o mú kí o séẹ́ṣé fún Jesu láti kún fún ẹ̀ṣẹ̀ ní ipò rẹ. Àbájadé rẹ̀ ni wípé ki o lè wa dúró níwájú Ọlọ́run nísisiyì láìní ẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀. ìbẹ̀rù tàbí àiyẹ Heberu 10:19; Romu 5:1.

# 5

# A DA Ọ LÁRE!

Kinni o túmọ̀ sí láti jàre? O túmọ̀ si kéde rẹ "láì jẹbi" Ni odò Ọlọ́run, o kò jẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀ kankan. Bíbélì sọ wípé "Njẹ́ bí a si ti ń dá wa láre nípa ìgbàgbọ́, àwa ni àláfíà lọ́dọ̀ ìgbàgbọ́, àwa ni àláfíà lọ́dọ̀ Ọlọ́run nípa Olúwa wa Jesu Kristi"Romu 5:1. A ti da ọ láre! Jesu ti gba ìyà ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nígbàtí o kú lórí agbélèbú lótítọ́ ko jẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀ kankan I Peteru 2:22. Ìdí si nìyí ti Ọlọ́run kò fi ka ẹ̀ṣẹ̀ kankan si ọ lọ́rùn. Bíbélì sọ wípé èyí ni pé, Ọlọ́run wà nínú Kristi, o mba arayé làjà sọ́dọ̀ ara rẹ̀, kò sí ka ìrékọja ìlàjà le wa

lọ́wọ́ 2 Korinti 5:10.

# A YÀ Ọ́ SÍ MÍMỌ́

Ẹ jẹ́ kí a fojúnú wo ìṣẹ́jú díẹ̀, pe o ṣúbu sínú kòtò ara rẹ̀ wa ti dọ̀tí gan, ẹnikan wa wa láti gbà ọ wípé "o mu ọ jáde láti inú kòtò náà" Ohunkan ti o kù láti ṣe ni kí o si wẹ ara rẹ mọ́. Ni ọ̀nà míràn "Kí o mu kòtò jáde lára rẹ̀, ṣùgbọ́n eleyí yóò gba àkókó àti ìgbìyànjú **I Kortinti 6:11** sọ wípé "Bẹ́ẹ̀ li àwọn ẹlòmíràn nínú yin si ti jẹ́ ri, ṣùgbọ́n a ti wẹ̀ yin nù, ṣùgbọ́n àti sọ yin di mímọ́, ṣùgbọ́n àti da yin láre li orúkọ Jesu Kristi Olúwa, àti nípa Ẹ̀mí Ọlọ́run

wa" Ìpele méjì ni ìsọdímímọ́ pín sí inú kòtò, èyí ti o túmọ̀ si wípé àti tún ọ bí àti lójúkan áà, Bíbélì kéde rẹ̀ pé o di mímọ́; a ya ọ kúrò nínú ayé si ọ̀dọ̀ Ọlọ́run o wa nílò láti jáde kúrò nínú kòtò jíjọ̀wọ́ ọkàn rẹ̀ fún ìwẹ̀númọ́ Óìsọdọ̀tunÒ nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run **Romu 12:2** sísọdọ́tun ọkan rẹ jẹ́ ìlàjà ti o tẹ̀síwájú. A kọ ọkan rẹ láti máa ronú ni ọ̀nà kan, láti máa rí nǹkan kí o tó gbààgbọ́. Nibayì, nípa ìsọdọtun ọkan rẹ, o gba ọkan rẹ làáyè láti máa ri nǹkan ni ọ̀nà ti Ọlọ́run àti ni èsì láti inú ọ̀rọ̀ rẹ̀.

**7**

# A TI GBÀ Ọ́

Kia máa dúpẹ́ lọ́wọ́ Baba, ẹniti o mu wa yẹ láti jẹ alábapin nínú ògun àwọn ènìyàn mímọ́ nínú ìmọ́lẹ̀. Ẹniti o ti gbà wa kúrò lọ́wọ́ agbára òkùnkùn, ti o si si wa nípo sínú ìjọba àyànfẹ́ ọmọ rẹ̀ **Kolose 1:12-13.**

Láti àkókò ti o ti fi ayé fún Jesu Kristi Olúwa wa, o ti di ọmọ ìjọba Ọlọ́run. Kò sí Èṣù kan láti ipò òkú kankan ti o lè pa ọ lára mọ báyì, o ti di òmìnira kúrò lọ́wọ́ májẹ̀mú ki májẹ́mú tí o ti wa bóyá o mọ̀ tàbí o kò mọ́, o

dòminira kúrò lọ́wọ́ ìhùwàsí, ẹ̀ṣẹ̀, àìsàn, àrùn èyí tí o fi ọ́ sínú ìgbẹ̀kùn. Kinni ìdí? Nítorí a ti gbà ọ́ kúrò lọ́wọ́ agbára òkùnkùbn! Bíbélì sọ wípé Ọlọ́run ti gbà ọ́ kúrò lọ́wọ́ ìsàkóso ìjọba òkùnkùn o si mu ọ wà sínú ìjọba rẹ o kò nílò láti bẹ̀rù mọ. Ọlọ́run ni olùṣọ́-Àgùtán rẹ ojú ààbò rẹ yóò wà lórí rẹ nígbàgbogbo **Orin Dafidi 23:1.**

Bíbélì sọ wípé - Nítorí náà bi ọmọ ba sọ yín di òmìnira, ẹ o di ominira nítóòtọ́" **Johannu 8:36** Ọlọ́run ti gba ọ sínú ìjọba rẹ, ibẹ̀ ni o wa báyì, a ti gbà ọ kúrò lọ́wọ́ agbára òkùnkùn. Kíyèsi wípé ọ̀rọ̀ ti a ti kọjá ni a ti gbà ọ là tẹ́lẹ̀ kúrò lọ́wọ́ ipá ti òkùnkùn.

## 8

# ẸMÍ ỌLỌ́RUN N GBÉ INÚ RẸ

Afikún míràn tí ó tún ga nínú ìyè titun yi ẹ̀mí Ọlọ́run wa ń gbé inú rẹ. Nígbà tí Ẹ̀mí Ọlọ́run bá fi inú rẹ sebùgbé. On tan ìmọ́lẹ̀ si ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti fún ọ ni òye titun nínú ọ̀rọ̀ náà. Torínáà báyì, nígbàtí o ba ń ka Bíbélì, wa ni òye titun nínú Ẹ̀mí rẹ,. èyí ti yóò wúlò fún ayé rẹ. Ohun míràn ti Ẹ̀mí Mímọ́ tún ń ṣe ni láti máa ran ọ létí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run **Johannu 14:26.** Ni àfikún, o tún fún ọ ni agbára láti jẹ ajèrè ọkàn to múnádoko nínú ìhìnrere ti Jesu Kristi.

Sùgbọ́n ẹ́yin ó gbà agbára, nígbà tí Ẹ̀mí Mímọ́ ba bà le yin, ẹ o máa ṣe ẹlárí mi ni Jerusalemu ati ni gbogbo Judea àti ni Samariìa, ati títí de òpin ilé ayé Iṣe **Awon Aposteli 1:8**.

# 9

# KINNI WÀÁ ṢE NÍGBÀTÍ...

## ÈRÒ TI KO TỌ́ BA WA SI ỌKAN RẸ̀?

Jíjẹ́ àtúnbí, kò sọ wípé a kò le dán ọ wò, ṣùgbọ́n o ko gbọdọ̀ gba ìdánwò náà. Bíbélì kọ́ wa wípé nígbàkùgbà ti ìdánwò ba dé, Ọlọ́run máa ńlá ọ̀nà àbáyọ **I Korinti 10:13**. Torínà ìgbà ti èrò àìtọ́ ba wá sínú ọkàn rẹ, o gbọdọ̀.

### (1) RÁNTÍ PÉ O JẸ ẸDÁ TITUN

Èrò yìí wa bi agbára àti ode, bi ìdánwò

láti ọ̀dọ̀ èṣù. O kò da láti inú ọkàn rẹ, pàápàá jùlọ nígbàtí o ti di àtúnbí. Bíbélì sọ wípé Óàwa ti a gbàgbọ́ nínú àtúnbíÒ a ni ọkàn ti Kristi **I Korinti 2:16.** O gbọdọ̀ máa rántí ẹniti o jẹ́ báyì, ẹ̀dá titun! Ọlọ́run fẹ́ wà láti  máa rántí pé ẹ̀dá titun ni a jẹ́ àti wípé o ti fún wa ni ìyè titun. Ìyè titun yìí jẹ́ ohun ti o gbọdọ̀ gbàgbọ́ nínú rẹ̀..

## (2) RÌN NÍNÚ ÌGBỌ́RÀN

Gbọ́ran si Ọlọ́run! Ká sọ wípé èrò ìwà búburú to ọ wa, ti títẹ̀ rẹ si pọ lápọ̀jù lórí rẹ láti ṣe ohun àìtọ́, o tilẹ̀ le ti dáwọ́ lé e. Ṣùgbọ́n ni ibẹ̀ náà, nígbà tí o ba rántí pé o ti di àtúnbí, ènìyàn titun, lójúkan náà fi ìgboya páti/fisílẹ̀. Gbọ́ràn si Ọlọ́run! Ṣé o rí. Didi àtúnbí ko túmọ̀ si wípé àwọn èrò búburú kò ni máa tọ̀ ọ́ wá, ṣùgbọ́n ṣùgbọ́n ohun to ṣe pàtàkì ni pe kí o máa gbá wọn láàyè láti le borí rẹ. Ko wọn jálẹ̀ ẹnikan ti sọ tẹ́lẹ̀ ri wípé o lè dí ẹyẹ lọ́wọ́ láti máa fò lórí rẹ, ṣùgbọ́n o lè da á dúró láti

kọ́ ìtẹ́ rẹ síbẹ̀.

O lè máa le dá àwọn èrò wọ̀nyìí láti máa tọ́ ọ wa ṣùgbọ́n o lè da wọn dúró láti máa fi inú rẹ ṣe ibùgbé má ṣe gbá ki wo ni ìjọba tàbí lágbára lórí rẹ, o lè da wọn dúró nípa níní èrò lórí àwọn nǹkan to tọ́tọ́ **Filipi 4:8**

Bóyá òṣèré orí-ìtàge ni ọ jẹ́, ti o wà fẹ́ ṣe bí obìnrin, lótítọ́ ọkùnrin ni o jẹ́, wa wọ aṣọ obìnrin àti gbé irún obìnrin sórí, ṣe bi obìnrin àti sọ̀rọ̀ bi obìnrin, ṣùgbọ́n o kò lè gbàgbé wípé ọkùnrin ni ọ́ lẹ́yìn ti o ba seré tán, wá kúrò lórí ìtàgé wa padà sínú yárà ìmúra, pàrọ̀ si ẹniti o jẹ́ wa si máa rìn lọ ni ìloro.

Nígbàti o ba di ọjọ́ Ajé ti o ń lọ sí ibi iṣẹ́ o kò lè gbàgbé pe ọkùnrin ni ọ wa rìn àti sọ̀rọ̀ bí ọkùnrin. Yóò jẹ́ nǹkan yẹ̀yẹ́ nígbàtí o bá padà si ibiṣẹ́ tí o wá bẹ̀rẹ̀ si ni sọ̀rọ̀ tàbí hùwà bí obìnrin, ni ọ̀nà ti o gbà fi seré lórí ìtàgè lálẹ́ àná.

Bákan náà ni o rí fún ọ nisisiyi on ṣe ohun

àìtọ́ nígbàtí o ti di àtúnbí ṣùgbọ́n nisisyi o ni ìyè titun. Ìyè titun tí o ní yìí ni ó yẹ ki o máa lo báyì. O tí ṣe ojúṣe obìnrin fún ọjọ́ pípẹ́ àtipé nígbà míràn o ti gbàgbé ara rẹ̀, wa si bẹ̀rẹ̀ si tún ṣe bi ọ̀kan nínú wọn ṣùgbọ́n o wa tún rántí pe ọkùnrin máa ni ọ, o sì wá ṣe àtúnṣe, o wa sọ wípé "Oh èmi kì í ṣe obìnriìn, nmi ò si lórí ìtàgé, mo ní láti jẹ́ ẹniti mo jẹ́ gan. Ọ́nà yìí ni o lè gba da àwọn ìhùwàsí tí kò dára dúró sọ fún ara rẹ wípé "wo" àtúnbí ni mi. Ìṣẹ́dá mi gan nìyí! Irú ìwà náà kó jẹ́ nígbstí o bá rántí Óèyí wa si rántíÒ DÚRÒ! sọ fún ara rẹ̀, "Mo ti di àtúnbí! kì ío sí dá dúró níbẹ̀".

Má jẹ́ ki ẹsẹ̀ tẹ̀síwájú, má sì ṣe tijú láti sọ fún ẹnikẹ́ni ti ẹba jọ dẹsẹ náa "oh ma bínú mi o le se eleyí mọ́, nítorí mo ti di àtúnbí "palẹ̀ ìwà búburú mọ́ nípa hihu àwọn ìwà tó dárá mọmọ ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyìí, wa àwọn ìwà tí o bá ti Ọlọ́run mu nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀, kí o si fi kọ́ ara rẹ̀ nípa fifi wọ́n sínú ìṣe.

# (3) JẸ OLÙṢE, FI ỌRỌ̀ SI ÌṢE

Ọlọ́run kò fẹ́ kí o jẹ olùgbọ́ nìkan, ṣùgbọ́n olùṣe ọ̀rọ̀ náà.

Ṣùgbọ́n ki ẹ jẹ́ olùṣe ọ̀rọ̀ náà ki o máa siṣe olùgbọ́ nìkan, kí ẹ máa tán ara yin jẹ́. Nítorí bí ẹnikan ba jẹ́ olùgbọ́ ọ̀rọ̀ náà, ti kò si jẹ́ olùṣe, on dàbí ọkùnrin ti o ń ṣàkìyèsí ara rẹ̀, o si ba tirẹ̀ lọ lojúkan náà o si gbàgbé bí on ti ri" **Jakobu 1:22-24.**

O jẹ́ olùṣe ọ̀rọ̀ nígbà tì o ba rántí ọ̀rọ̀ ti o si fi si iṣe bi o tí yẹ. Wa si máa ránti nígbàgbogbo ọ̀kan nínú àwọn ohun ti Ẹ̀mí Mímọ́ ń ṣe nínú wa nìyí. Jesu sọ wípé "ṣùgbọ́n olùtùnnú náà, Ẹ̀mí Mímọ́, ẹniti Baba yóò rán li orúkọ mi, on ni yóò kọ yin li ohun gbogbo, yóò si rán yin létí ohun gbogbo ti mo ti sọ fún yin". **Johannu 14:26.**

A dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run pe Ẹ̀mí Mímọ́ náà wa nibiyí; o ń ràwálọ́wọ́ láti le rántí ọ̀rọ̀ náà. Nígbà

tí o ba rántí ọ̀rọ̀, o ni láti gbe ìgbésẹ̀ lórí rẹ, fi ọkan lélẹ̀ nípa rírántí; Ẹ̀mí Mímọ́ yóò mu wa si ìrántí rẹ. Ṣùgbọ́n o gbọdọ̀ setán láti gbọrán nígbàtí o ba mu àwọn òtítọ́ náà wá si ọakn rẹ.

## (4) RÁNTÍ PE ẸṢẸ̀ KÒ LE NI IPÁ LÓRÍ RẸ̀.

O ní láti máa rántí ohun kan wípé: Èrò àìtọ́ kò lágbára láti jẹ gàba lórí rẹ ti o ko ba gbàá láyé. "Nítorí ẹ̀ṣẹ̀ ki yóò ni ipa lórí yin..." **Romu 6:14.** Ẹ̀ṣẹ̀ kò lè jẹ́ Olúwa lórí rẹ, nítorí o kò sí lábẹ́ òfin ọgbọ́n lábẹ́ ore-ọ̀fẹ́. Èyí si ni ohun ti Bíbélì sọ nípa rẹ. Ọlọ́run ti gba ọ lọ́wọ́ agbára ẹ̀ṣẹ̀ àti òkùnkùn, o si gbà ọ́ sínú ìjọba rẹ̀.

"Kí a máa dúpẹ́ lọ́wọ́ Baba, ẹniti o mu wa yẹ láti jẹ alábápín nínú ogun àwọn ènìyàn mímọ́ nínú ìmọ́lẹ̀. Ẹniti o ti gbà wa kúrò lọ́wọ́ agbára òkùnkùn, ti o si si wá nípo sínú ìjọba àyànfẹ́ ọmọ rẹ. **Kolose 1:12-13.**

Ibiti o wá nisisiyi báyì nígbàtí o ti di àtúnbí, ìdí si nìyí ti agbára òkùnkùn kò fi le borí jọba lórí rẹ, wa wa ni ìpele ti ẹ̀ṣẹ̀, ṣùgbọ́n ìwọ wa ni ìpele ìyè ti Ọlọ́run, èyí tí o gá ju ẹ̀ṣẹ̀ lọ. Ṣe o wa ri wípé wọn o lé jọba lórí rẹ.

**Kolose 1:14** sọ wípé "Nínú ẹniti àwa ni ìdáǹdè nípa ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ àni ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀". Nínú Kristi Jesu, a ni ìdándè. Èyí ni ohun ìní-àkọ́kọ́ yìí **Efesu 2:5-6.** A kò sakitiyan láti nii, a ti ni bayì! a gbọdọ̀ ni ìmọ̀ohùn ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yìí kí a si máa yọ̀ nínú rẹ̀.

**10**

# KINNI WÀÁ ṢE NÍGBÀTI…..

## Ọ̀RẸ́ ÀTIJỌ́ N GBÌYÀNJÚ LÁTI KO ÌRẸ̀WẸ̀SÌ BÁ Ọ

Ní báyì ti o ti di àtúnbí o ti di ara ìdíle tuntun. O kìí ṣe ara àwọn ìdílé ti àtijọ́ mọ́. Èyí kò si túmọ̀ si pé kí o pa àwọn ọ̀rẹ́ àtijọ́ rẹ ti tàbí kọ̀ wọn pátápátá. O yẹ ki ó jẹ́ ìmọ́lẹ̀ fún wọn. Wọn si tún wa nínú òkùnkùn, nítorí wọn kò ní Jesu Kristi nínú ọàn wọn. O ni láti rwntí wípé ìwọ ni ìmọ́lẹ̀ Ọlọ́run fún wọn. Pín ìhìnrere pẹ̀lú wọn kí àwọn pẹ̀lú le má tẹ̀lé Jesu.

Kinni o yẹ ki o ṣe nígbstí wọn ba gbìyànjú láti mu irẹ̀wẹ̀sì bá ọ?. Bíbélì sọ wípé ni ọjọ́

ìkẹhìn, àwọn ẹlẹ́gan yóò dé pẹ̀lú àwọn ohun àìtọ́ gbogbo ti wọn ro àti máa fi ótítọ́ rẹrìn **2 Peteru 3:3-4.** Ẹlẹ́gan ni àwọn ti o gbìyànjú láti mu ọ padà si ìgbé ayé rẹ ti àtijọ. Síbẹ̀ o ní láti kọ jálẹ̀. Kọ láti gba ìhùwasi ko di ọ lọ́nà ìbádàpọ̀ rẹ pẹ̀lú Jesu Kristi máṣe ba àìgbàgbọ́ wọn dọ́gbà. Mó gb ìmọ̀ràn wọn dípò bẹ́ẹ̀, dúró lórí ìpín rẹ pẹ̀lú Ọlọ́run àti ọ̀rọ̀ rẹ̀.

## ÌDÀPỌ̀ ÀÌDỌ́GBA

Oko dìda ni ìgbà àtijọ́, àgbẹ̀ yóò sọ àwọn ẹranko méjì papọ̀. Fún àpẹẹrẹ, kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ méjì tàbí málùú méjì, wọn o so wọn pọ̀ láti fi sàgbẹ̀. Àwọn ẹranko méjèèjì wọ̀nyìí yóò máa kọ ilẹ̀ bi wọn ti ń lọ papọ̀ nítorí wọn ti so wọn papọ̀, àwọn ẹranko méjì yìí ni láti máa rìn ni ipa ọ̀nà kan náà. Nibikibi ti ékinni bá lọ, ni ekejì náà yóò lọ. Àgbẹ̀ náà ni yóò ma dárí wọn, wọn si gbọdọ̀ lọ si ọ̀nà kannà nítorí wọn wa lábẹ́

àjàgà kanna.

Níbayì, ti àwọn mejèèjì ba jẹ́ kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ a o pe wọn ni àjàgà dídọ́gbà ṣùgbọ́n ti ọkàn ba jẹ́ kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ ti ekejì sí jẹ́ màálù, wọn o pe wọn ni "àjàgà àìdọ́gbà" Ónítorí wọn kìí ṣe irú kan náàÒ. Tí a ba fẹ sopọ̀ papọ̀ pẹ̀lú ẹnikan o ni láti "dọ́gbà" ẹniti ó jẹ́ kristiani àti kristiani ni o gbọdọ̀ máa rìn papọ̀ bi ẹlẹ́gbẹ́ jẹgbẹ́. Ṣùgbọ́n nígbstí onígbàgbọ́ àti àláìgbàgbọ́ ba kẹ́gbẹ́ papọ̀ wọn ni ìdàpọ̀ àìdọ́gbà. Ọlọ́run si ń sọ wípé. Ẹ maṣe fi aìdọgbà dàpọ̀ pẹ̀lú àwọn àláìgbàgbọ́ **2 Korinti 6:14-16** ṣe o wa rí, ti ìwọ àti àwọn alaigbagbọ́ ni ẹ ba jọ ń kẹ́gbẹ́, gbé ìgbé aye kan náà, a jẹ́ wípé o wa ni ìdàpọ̀ aídọ̀gbà pẹ̀lú wọn kò sí tọ́. Ọlọ́run kò fẹ́ ki o wa nínú àjàgà pẹ̀lú àwọn kristiani míràn, ma ṣe ohunkan náà pẹ̀lú wọn. Alaigbagbọ́ kò le jẹ́ ọ̀rẹ́ kòríkòsun rẹ́. Ko si bi ènìyàn náà ti léko to, níwọ̀n ìgbàtí kò ti di àtúnbí kò lè jẹ ọ̀rẹ́ rẹ. Kò lè ṣeéṣe kò sí tún jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà níwájú Ọlọ́run nítorí

o jẹ́ ìdàpọ̀ àìdọ̀gba. Ìwádìí rẹ gẹ́gẹ́ bí ẹnìkan le máa wa ni ìwọn pẹ̀lú àgbéyẹ̀wò ti Ọlọ́run.

Níkété, ti Ọlọ́run ran Samueli lọ si ìdílé Jesse láti lo fi òróró yan ọmọ rẹ̀ kan láti di ọba ni Isreali **I Samuel 16:1-13.** Nígbàtí Samueli kọ́kọ́ ri àkọ́bí Jesse, Eliabu, Samuel sọ wípé "dájúdájú èyíì ni yóò jẹ́ ẹni àmì òróró Olúwa, ni ojú rẹ, nítorí ti o sìngbọnlẹ̀, ga àti rẹwà. Ṣùgbọ́n Ọlọ́run ba wòólì sọ̀rọ̀ wípé, máṣe fi òróróyan, nítorí Èmi ti kọ ọ o tún sọ wípé "Nítoríì èniyàn nwo ojú Ọlọ́run nwo ọkàn".

Nítorínáà ìwòye rẹ bi ẹnikan o dúró lórí wíwo ojú. Ohun ti o sọ, bi o se rí, bi o ti se nrìn, o le ro gbogbo àwọn ipinu yìí nípa rẹ, lórí àwọn nǹkan wọ̀nyìí, ṣùgbọ́n se o ri, Ọlọ́run wa ọkan. Ẹniti ko ti di àtúnbí ko ni ẹ̀mí ti o tọ́ pẹ̀lú Ọlọ́run. Ọ̀nà kan ti èniyàn le gba láti wa ni títọ́ pẹ̀lú Ọlọ́run ni didi àtúnbí. Ìgbà yìí gan ni èniyàn yẹ láti jẹ ọ̀rẹ́ korikòsún rẹ. Títí o fi di àtúnbí, ko le jẹ ọ̀rẹ́ rẹ. Ko ti yẹ fún ìpé wọn

ti Ọlọ́run. Nisisiyi ti o ti di àtúnbí, ìfẹ́ rẹ ọkan rẹ gbọdọ̀ jẹ láti tẹ Ọlọ́run lọ́run. Torínà o ko gbọdọ̀ lo ìgbélé wọn ti ara rẹ, èyí ṣe pàtàkì fi ọkan rẹ pamọ́ nínú ti Ọlọ́run yóò ṣi mu ọ la a ja **I Korinti 10:13.**

# 11

## KINNI WA ṢE E NÍGBÀ

## TÍ INUNIBINI ÀTI ÌPÒNGBẸ̀ BÁ DÉ.

Nínú **Marku 4:1-9** Jesu sọ fún wa owe afúrúgbìn. Arákùnrin náà lọ fúrúgbìn irúgbìn rẹ díẹ̀ bọ sórí àpáta, díẹ̀ bọ sí àrìn ẹ̀gún àti òmíràn lọ sí ilẹ̀ rere. Ni ẹsẹ 16 àti 17 Bíbélì sọ wípé "àwọn wọ̀nyìí pẹ̀lú si ni àwọn ti a fún sórí àpáta, àwọn ẹniti nígbàtí wọn ba gbọ́ ọ̀rọ̀ náà, lójúkan náà n wọn a fi ayọ̀ gbàà. Wọn kò si ni gbongbo nínú ara wọn, ṣùgbọ́n wọn

a wà fún ìgbà díẹ̀: lẹ́hìn náà, nígbàtí wàhálà tàbí inúnibini ba dìde nítorí ọ̀rọ̀ náà, lojúkan náà wọn o kọsẹ̀ O ń sọ̀rọ̀ nípa àwọn ti kò ní gbòngbò nínú ara wọn. Ṣùgbọ́n wọn a wa fún ìgbà díẹ̀ o sọ wípé irú àwọn ènìyàn bẹ́ẹ̀ wọn ń fi ayọ̀ gba ọ̀rọ̀ náà, nígbàtí wàhálà tàbí inunibini ba dìde nítorí ọ̀rọ̀ náà, wọn a kọsẹ̀. èyí tí sẹlẹ̀ si ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn.

Ohun ti jesu ń sọ nibiyi ni pé ọ̀pọ̀ ènìyàn ti wọn ko ní ìfẹ́ to jìnlẹ̀ fún un…inú wọn dùn nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nítorí ìlérí ti ìyè ayérayé, ìdùnnú, àti ìdáhùn àdúrà,

ṣùgbọ́n kìí ṣe pe wọn ni ifẹ́ Ọlọ́run de inú, nígbàatí inunibini ba wa de, wọn o kọsẹ̀. Èyí bani nínú jẹ́! Nígbàtí wàhálà àti inunibini bá dé ohun ti ó yẹ ki o ṣe ki o tẹ̀lé ọ̀rọ̀ rẹ̀!

## (1) O GBỌ́DỌ̀ NI ÌFẸ́ TO JÌNLẸ̀ FÚN ỌLỌ́RUN

Ọlọ́run fẹ́ ki o ni ìjinlẹ̀ ìfẹ́ ti o dúró fún òun. Ìfẹ́ le pọ̀si tàbí dínkù. Bi o tiṣe ń ronú nípa rẹ sí, tẹ́tísílẹ̀ si ọ̀rọ̀ rẹ̀ àti ni ìbàdàpọ̀ pẹ̀lú rẹ́ nínú àdúrà, ìfẹ́ ńlá ni o ni fún, nítorí ni dídá ọ̀rẹ́ ìfẹ́ máa ń pọ̀si ni. Bi o ti n mọ Ọlọ́run si, bẹ́ẹ̀ ni ìfẹ́ rẹ yóò máa pọ̀ sí. Bi o ti gbọ́ ọ̀rọ̀ rẹ si, bẹ́ẹ̀ náà ni wa máa ṣe àwárí ìfẹ́ rẹ́ si àti fẹ́ran rẹ̀ si, bẹ́ẹ̀ si ni wa máa ri gbà si.

Ti o ba ni ìfẹ́ to lágbára yìí fún Ọlọ́run, ọ̀rọ̀ rẹ yóò wa ni gbongbo nínú ọkan rẹ̀. Ti o fi jẹ wípé ki o ba ń dojúkọ́ ìṣòro kísòro, o mọ ìhà ti Ọlọ́run kọ si ọ wa si máa kéde ohun ti Ọlọ́run sọ nípa rẹ̀. Bíbélì sọ pé ìyé àti ikú wa nínú ipa ahọ́n **Owe 18:20-21** àti láti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun inú ni ẹnu ṣọ Matteu 12:34-35-37. Ti ọkàn rẹ ba kún fún ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, ohun yówù ti o le de, wa máa ri ohun gbogbo ni ọ̀nà ti Ọlọ́run àti sọ ohunkan náà yóò si wa si ìmúsẹ.

## (2) MÁṢE JỌ̀WỌ́ RẸ̀ SÍLẸ̀

O kò gbọdọ̀ jọ̀wọ́ rẹ sílẹ̀ nígbà tí wàhálà bá dìde! Didi àtúnbí ko túmọ̀ sí wípé wàhálà ò ni dìde tàbí wípé kò ni sí ìdánwò. Ohun ti ó kan túmọ̀ si ni wípé nínú gbogbo àwọn ìṣòro wọ̀nyìí Ọlọ́run yóò mu ọ làjà. Bi o ti wa nínú **Orin Dafidi 23:5** ìwọ tẹ tábìlì onjẹ sílẹ̀ níwájú mi li ojú àwọn ọ̀tá mi, o lè wa ni wájú àwọn ọ̀tá rẹ, ṣùgbọ́n kò lè pa ọrun inunibini kò lè pa ayé rẹ run. Ọlọ́run kò fẹ́ ki o jọ̀wọ́ rẹ sílẹ̀, o ní láti dúró tirii! Kò ní ṣe bi o tilẹ tó tàbí le kókó tó ni ojú rẹ, máṣe jọ̀wọ́ rẹ sílẹ̀! Ọlọ́run yóò mu ọ la a já. Torínáà màṣe rẹ̀wẹ̀sì. Dúró nínú ìgbàgbọ́ rẹ sii ko si ni kọ ọ tàbí já ọ kulẹ̀. wa máa borí nínú gbogbo ayídayida ayé yìí, nítorí wọn ṣe kókó si ọ. **Isaiah 43:2** sọ wípé Nígbàtí ìwọ ba ńlá omi kọjá, emi o pẹ̀lú rẹ, àti láàrìn odò wọn kí yóò bo ọ́ mọ́lẹ̀ nígbàtí ìwọ ba n rin nínú iná, ki yóò jo ọ. Nígbà ti o

ba ntẹ̀lé Jesu Kristi, sin ni pẹ̀lú gbogbo ọkàn rẹ̀. Tẹ̀lé lábẹ́ àkóso botilẹ̀ wu kó rí.

"Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run ẹniti o fi ìṣẹ́gun fún wa nípa Olúwa wa Jesu Kristi. Nítorí náà ẹ̀yin ara mi olùfẹ́ a máa dúró sinsin, láìyẹsẹ̀, ki ẹ ma pọ̀ sí ni iṣẹ́ Olúwa nígbàgbogbo, níwọ̀n bi ẹ̀yin ti mọ̀ pé iṣẹ́ yin kìí asán nínú Olúwa"

**I Korinti 15:57-58.**

"Nínú olúkùlùkù ẹniti a bi nípa ti Ọlọ́run o ṣẹ́gun ayé: èyí si ni ìṣẹ́gun ti o ṣégun ayé, àní ìgbàgbọ́ wa **I Johannu 5:4.** Ṣe o ri Ọlọ́run ti fún wa ni ìṣẹ́gun nípasẹ̀ Jesu Kristi Olúwa a kò lè pàdánù **I Johannu 5:4** farabalẹ̀ kaa. O ń sọ̀rọ̀ nípa ìṣẹ́gun ti o ti borí ayé, èyí tí o jẹ́ ìgbàgbọ́ wa. Ma gbe ni àìgbàgbọ́, aṣẹ́gun ni o jẹ́ nítorí a bí ọ nípa ti Ọlọ́run. O jẹ́ ọmọ Ọlọ́run ti a bi nípa Ẹ̀mí rẹ̀.

**12**

# ÌWỌ ÀTI ẸMÍ MÍMỌ́

Láti di àtúnbí ni láti bi ọ nípa Ẹ̀mi ti Ọlọ́run **I Korinti 12:13; Johannu 3:5-8.** Nígbàtí o di àtúnbí Ẹmí Mímọ́ wa jẹ́ ara ayé rẹ. Torínà o ní láti ni òye ẹniti ó jẹ́ àti da àwọn iṣẹ́ rẹ̀ mọ̀.

O gbọdọ̀ ni òye, ohun ti o mú wá fún o, ki o ba le gbàdún ìyè lọ̀pọ̀lọpọ̀ ti a ni nínú Kristi kí o si gba ẹ̀bùn náà. **Luku 24:49**. Iṣe Àwọn **Aposteli 1:4-8** wa fún ọ nípasẹ̀ rẹ.

# TANI Ẹ̀MÍ MÍMỌ́?

Nínú àwọn Bíbélì ni ọ̀nà to yàtọ̀ ni a ti ri ti wọn dárúkọ Ẹ̀mí Mímọ́.

Nínú májẹ̀mú láéláé, a ri ti o ń fi agbára àti le ṣe ohun ti o jù bí o ti yẹ lọ Onidajọ **14:6, 19.** Nínú májẹ̀mú titun ari ti o tún dàyàtọ̀ nínú ìbí, iṣẹ́-ìránṣẹ́ àti nínú ìyè ti jesu **Luku 4:18.** A tún ri Ẹ̀mí Mímọ́ nínú Ise Awọn **Aposteli 2:1-4** tí o ń ṣiṣẹ nínú ayé àwọn ọmọ ẹ̀yìn Jesu. Òun ni Ọlọ́run, Alágbára ènìyàn àtiÒun ni mẹ́talọ̀kan **Johannu 14:16, 17, Johannu 15:26.**

O ti wa ni ayé láti ìgbà ni **Genesisi 1:2** Òun ni àkọsílẹ̀ agbára Ọlọ́run, ni ọ̀nà míràn, Òun ni ipa Ọlọ́run ti o mú ohunkóhun ti Baba sọ wa si ìṣe **Genesisi 1.** Òn ni Ẹ̀mí ìfẹ́, agbára àti ọkàn tó yè koro **2 Timoteu 1:7.** O n ni èmi ominira **2 Korinti 3:17**

## KINNI ẸMÍ MíMỌ́ KÒ JẸ́?

Ó dára ki a ṣe àkíyèsí pé Ẹmí Mímọ́ ko jẹ́ ipá, afáfá òróró tàbí Àdàbà, lòótọ́ láti inú ìwé mímọ́, a ri ti wọn lo wọn bi ohun ti o dúró fún. Kì í ṣe "ahọ́n" lòótọ́ ni o fún wọn ni ohùn láti sọ̀rọ̀, kì í se agbára ṣùgbọ́n o mu agbára Ọlọ́run wa fun wá, kì í ṣe ẹ̀mi ti o mu ọ wọ inú ìdè ti ìbẹ̀rù **Romu 8:15.** Ṣùgbọ́n ti òmìnira **2 Korinti 3:17.**

## KINNI IDI TI A FI NILO ẸMÍ MÍMỌ́?

Ẹmí Mímọ́ ń fún wa ni agbára àtòkè wá **Ise Awon Aposteli 1:8.** Gbólóhùn yìí "agbára" túmọ̀ láti int èdè Giriki "dunamis" ti o túmọ̀ si "agbára ìmúdàgbà láti fa àyípadà". Nígbà tí Ẹmí Mímọ́ wa láti ma gbe inú wa, o fún wa ni agbára láti yìí ohun padà nínú ayé wa àti ayé àwọn ẹlòmíràn.

Ó fún wa ni ìgboyà láti wàásù ìhìnrere **Matteu**

**28:18-20; Marku 16:15-18.** O n ń tọ́wa àti darí wa **Johannu 16:13 Romu 8:14.**

On tù wáá nínú **Johannu 14:L18;** Ise Àwon **Aposteli 9:31.**

On kọ́ wa ti ìtọ́ni wa Johannu **14:26; I Korinti 2:11-12**.

On rìn pẹ̀lú wa àti jẹ́ ipa ara ìgbé ayé ojojúmọ́ wa **Johannu 14:16.**

On jẹ́rì pẹ̀lú ẹ̀mí wa pe ọmọ Ọlọ́run ni a jẹ́ àti alábapin ọrọ̀ rẹ nínú Jesu Kristi **Romu 8:16; Efesu 3:6.**

O fún wa ni ominira láti súnmọ́ Ọlọ́run ni ìfẹ́ **Romu 8:15; 2 Korinti 3:17; 2 Timoteu 1:7**.

# O LÈ NÍ ÌBÁṢEPỌ̀ PẸ̀LÚ Ẹ̀MÍ MÍMỌ́

Nínú **Johannu 14:17** Jesu sọ wípé: Ani Ẹ̀ mí ótítọ́ ni, ẹniti aráyé ko lè gbà, nítorí tí kò ríi, bẹ́ẹ̀ ni kò sí mọ́ ọ: ṣùgbọ́n ẹ̀yin mọ̀ ọ́! nítorí

ti o mba yin gbé, yóò si wa nínú yin".

Láti ni ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Ẹ̀mí Mímọ́ ni láti da wíwà àti dá iṣẹ́ ìránṣẹ́ rẹ̀ mọ̀ nínú ayé rẹ̀. O wà gbọdọ̀ máa lo àkókò ni iwájú rẹ láti ba sọ̀rọ̀ àti láti mọ̀ ọ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rẹ́. O le ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú rẹ nípasẹ̀ lílo àkókò láti gbàdúrà àti kọ́ ẹ̀kọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti gbígbọ́ràn si Ẹ̀mí Mímọ́ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.

Nígbà tí o ti di àtúnbí, a ti tẹ-ọ-bọmi sínú ẹ̀mí ti Ọlọ́run. Láti tẹ̀bọmi jẹ́ rírì bọ inú nǹkan pátápátá. Fún àpẹrẹ o le mu bọ̀ọ́lù oní rọ́bà, kí o tẹ bọ inú àgbá omi ni ọ̀nà ti omi yóò fi bo gbogbo orí bọlú náà mọ́lẹ̀. Nǹkan ti o sẹlẹ̀ niyí nígbàtí o bá di àtúnbí-a ti tì ọ́ bọ́ omi, bi bọlú, sínú Ẹ̀mí Mímọ́. Njẹ́ o wa mọ wípé ohun kan ni fún bọlù láti jẹ́ kí omi borí rẹ̀ ohun ni ti o tún yàtọ̀ ni láti jẹ́ kí o kún àti ki omi bori rẹ̀. Fún bọlu náàa láti le kún fún omi, ọ̀nà gbọdọ̀ wa ti omi yóò gbà wọ inú omi. Ni ọ̀nà míràn, àwọn èròjà ara bọlu gbọdọ̀ gba omi láàyè láti le wọ

inú rẹ̀. Ní ọ̀nà kan náà, nígbàtí o ba di àtúnbí, o ní láti gbà Ẹ̀mí Mímọ́ sínú rẹ láti kún ọ.

Bakán náà kíkún fún Ẹ̀mí Mímọ́ ki iṣe ìrírí ti o ń wáyé lẹ́kan ni ìgbà ayé èniyàn. Dípò bẹ́ẹ̀ o jẹ́ ohun ti o máa ń ṣẹlẹ̀ lemọ́lemọ́, ni ojojúmọ́ **Efesu 5:18.** Ẹ̀yí sọ nípa ìmọ̀ohùn ìwà láàyè rẹ àti ni dídá mọ̀ iṣẹ́ ìránṣẹ́ rẹ nínú ayé rẹ, o le máa kún fún Ẹ̀mí Mímọ́ bi o ti ń dàgbà nínú ìdàpọ̀ rẹ pẹ̀lú rẹ̀ nípasẹ̀ ìyìn àdúrà, àti kíkọ́ ẹ̀kọ́ ọ̀rọ̀ rẹ nígbà gbogbo àti ni tẹ́tí si àwọn ìtọ́ní rẹ́ lọ́nà tí o tọ́. Ni ọ̀nà yìí Ẹ̀mí Mímọ́ le máa dárí rẹ̀.

## FÍFI ÈDÈ ÀÌMỌ́ SỌ̀RỌ̀

Gẹ́gẹ́ bí mo ti sọtẹ́lẹ̀, Ẹ̀mí Mímọ́ máa fún àwọn ọmọ Ọlọ́run ni ohùn láti sọ èdè àìmọ́. Ọkan nínú àwọn ààmì ti Olúwa sọ wípé yóò máa tẹ̀lé àwọn ti o ba gbàgbọ́ lọ nìyí wípé wọn o máa fi èdè titun sọ̀rọ̀ **Marku 16:17.**

Èyí jẹ́ nǹkan ti ẹ̀mí àti agbára ti o tayọ èyí ti àwọn onígbàgbọ́ fib a Ọlọ́run sọ̀rọ̀ tàrà láti inú Ẹ̀mí, ti o si ni ipa níìnú rẹ bi ẹ̀bùn ti Ẹ̀mí Mímọ́ fifi èdè àìmọ̀ sọ̀rọ̀ nígbà míràn a máa pe ni "gbígbàdúrà láti inú Ẹ̀mí, nígbà tí a ba n fi èdè àìmọ̀ sọ̀rọ̀, a n ba Ọlọ́run nìkan sọ̀rọ̀ **I Korinti 14:4** a si ń fi sẹs ara wa múlẹ̀ tàbí gbé ara wa ró **Juda 1:20.** Bákan náà Ẹ̀mi wa ń gba agbára àti àtúnṣe **Isaiah 40:31**

Tí o bá ti gba Ẹ̀mí Mímọ́, o lèé fi èdè àìmọ́ sọ̀rọ̀ nígbà ti o ba ti fẹ́. On kọ ni o sọ̀rọ̀ nípaṣẹ́ rẹ̀, ṣùgbọ́n o ń fun ọ ni agbára láti sọ ọ́. Torínà o lè tẹ̀síwájú láti ba Olúwa sọ̀rọ̀ ni èdè àìmọ́, nígbàkugbà ti o bá fẹ́.

Níìgbà tí o ba bẹ̀rẹ̀ si ni fi èdè àìmọ̀ sọ̀rọ̀, wá bẹ̀rẹ̀ si ni ìmọ̀ rẹ bi o ti fi hùwà lorekore. Ó dàbí ọmọdé ti o kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ àkọ́kọ́ rẹ díẹ̀. Bí o ba ti kọ ọ̀rọ̀ sọ si bẹ́ẹ̀ ẹni yóò ma ṣe deede. Bẹ́ẹ̀ni ni fífi èdè àìmọ̀ sọ̀rọ̀ náà, o jẹ́ èdè titun, síbẹ̀ o ko nílò láti máa kọ́ọ, wa ma sọ ọ deede

bi o ba ti sọ di iṣe rẹ.

Bákan náà, Bi o si ti ń fi èdè àìmọ̀ sọ̀rọ̀ nígbàkúgbà, yóò ma mu ọ dàgbà nínú ẹ̀mí, àti dárí rẹ si ipa àwọn ẹ̀bùn míràn àti se àfihàn Ẹ̀mí ti Ọlọ́run

# 13

# NJẸ́ O YẸ KÍ O MÁA LỌ SI SỌ́Ọ̀SÌ?/ILÉ ÌJỌ́SIN

Nínú **Matteu 16:18** Jesu sọ̀rọ̀ nípa ijọ rẹ, èyí ti o jẹ́ ara rẹ ni ayé, o wípé Èmi o kọ ijọ́ mi, ẹnu ọ̀nà ipo-òkú kì yóò sílé borí rẹ̀.

Nítorí gẹ́gẹ́ bí ara ti jẹ́ ọkàn, ti o si li ẹ̀yà púpọ̀, ṣùgbọ́n ti gbogbo ẹ̀yà ara ti iṣe púpọ̀ jẹ́ ara kan: bẹ́ẹ̀ si ni Kristi pẹ̀lú.

Nítorí pé nínú Ẹ̀mí kan li àti baptisi gbogbo wa sínú ara kan, ìba ṣe Ju, tàbí Hellene, iba ṣe ẹrú tàbí òmìnira, a si ti mú gbogbo wa mu nínú Ẹ̀mi kan **I Korinti 12:12-14.**

# ÀWA NI ARA KRISTI SI NI ORÍ

Gbogbo kristiani ÓàtúnbíÒ ni ẹ̀yá ara rẹ àti olúkùlùkù si jẹ́ ẹ̀yà ara rẹ

**I Korinti 12:27.** Gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà ara ènìyàn kọ̀ọ̀kan kò le dá iṣẹ́ se, ni ìyapa, àwọn ẹ̀yà ara ọ̀tọ̀tọ̀ ti Kristi kò lè síṣẹ́ to péye ni òun nìkan. Nítorí Ọlọ́run fi ẹ̀bùn ọ̀tọ́tọ́ àti ìpè rẹ fún ara ìjọ, ki gbogbo ìjọ ba le ní àǹfààní **I Korinti 12:18-24; Efesu 4:11-12.**

Lílọ si ilé ìjọ́sìn wa jẹ́ ìgbọ́ràn si ìfẹ́ Ọlọ́run àti mu wa láti le bùkún àti fi ẹsẹ̀ ara wa múlẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀bùn ọ̀tọ̀tọ̀ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, iṣẹ́ ìyanu, àsọ́tẹ́lẹ̀ abbl. O ni àǹfààní gba òye tó dára nínú ọ̀rọ̀ ti a ń kọ́, eri ti a ń gbọ́ àti ṣiṣé ẹlẹ́rí àwọn iṣẹ́-ìyanu gbìgbádúrà àti jíjọ́sìn fún Ọlọ́run lápapọ̀ èyí tí o mú ìfòròróyàn ti Àjọ wá ti Ẹ̀mí Mímọ́ ti o ń ṣe ìránṣá fún àwọn ọmọ ìjọ ni ọ̀nà kan pàtó **Heberu 10:25;** Iṣe Awọn **Aposteli**

**1:14; Orin Dafidi 133:1-2.**

Rìnrìn nínú ọ̀rọ̀ ni íwọ nìkan jẹ́ làálà gígasókè ni ígbà tí o ba dárápọ̀ mo ìjọ tí o kún fún Ẹ̀mí. Ni kíkópá nínú ìjọ ni ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ mú ọ mọ àwọn ọmọ ìjọ àti mọ nípa ìjo náà dárádárá. Wa tún máa dàgbà nínú ẹ̀mí ÓẸni inúÒ sí ìbàlágà. Èyí yóò jẹ́ ki rìnrìn nínú ọmọ́ rẹ rọ́rùn láti ṣo èso.

Gẹ́gẹ́ bí kristianì, o ní láti mọ ijọ agbègbè, ìjọ tí o lè pé ni ilé rẹ àti kí o máa kópa nínú gbogbo àwọn ètò/àsàyàn iṣẹ́-ṣíṣé. Tí kò bajẹ́ bẹ́ẹ̀ wa máa dùn ara rẹ ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìbùkún Ọlọ́rún àti wa si másа kúrò ni ìlànà ti ọ̀rọ̀ náà. Ní bàyí ti ó tí di àtúnbí, máa rìn nínú ìmọ̀ọhùn ẹniti o jẹ́, máa siṣe kọ ìpéjọpọ̀ àwọn àyànfẹ́ sílé **Heberu 10:26** máa lọ si ilé-ìjọ́sìn!

# DÍDÀGBÀ SÒKÈ

Bíbélì ṣe kìlòkìlò fún wa “sapọn láti fi ara rẹ hàn níwájú Ọlọ́rún ni ẹniti o *yege* , àṣiṣe ti kò ni láti tijú, ti o ń pín ọ̀rọ̀ òtítọ́ bù o ti *yẹ* **2 Timoteu 2:15.** Mo gbà ọ níyànjú láti máa lọ àwọn oríṣi àwọn ìwé wa fún ìdàgbà nínú Ẹ̀mí. Wọn kún fún ìkọ́ni àti ìfihàn tí a ṣe láti fihànọ bi o ti ṣe le so èso àti ni àbájáde ni gbogbo agbègbè nínú ayé rẹ, àti mu kí ìgbàgbọ́ rẹ dédé nínú ọkàbn rẹ́ láti da bẹ́ẹ̀.

Ra wọn, ṣe àṣàrò nínú wọn. Fi ọ̀rọ̀ náà si iṣe àti máa ri ìyípadà ológo nínú ayé rẹ̀!.

## Láti ba òǹkọ̀wé yìí sọ̀rọ̀ kọ..

Olùṣọ́-Àgùtàn Chris Oyakhilome:


Apapọ̀ ìjọba gẹ̀ẹ́sì

Unit C2, Thames View
Business Centre
Barlow Way, Rainham
Essex, RM13 8BT
Tel: +44(0)170 855 6604

Gusu Afrika:
303 Pretoria Avenue
Cnr. Harley and Bram Fischer,
Randburg, Gauteng, South Africa.
Tel:+27-11-326 0971,
+27-11-326 0972

Nigeria:
Christ Embassy
Plot 97, Durumi District,
Abuja, Nigeria.

***Nigeria:***
Plot 22/23 Billings Way, Oregun,
Ikeja, Lagos.
Tel: +234-808 586 5700,
+234-817 198 7339
+234-802 478 9892-3

# ÀWORO IWE MÍRÀN TI OLÙṢỌ-ÀGÙTÀN **CHRIS OYAKHILOME**

- ÀSỌTẸ́LẸ̀: - Ní òye agbára tí o ń dárí -la rẹ
- Bí o ṣe le mú ìgbàgbọ́ sisẹ́
- Bí o ṣe le mú ìgbàgbọ́ sisẹ́
- Agbára ahọ́n
- TÀwọn ìlẹ̀kún Sion
- Darapọ̀ mọ́ àwọn kẹ̀kẹ́
- Máṣe dúró níbí!
- Àwọn ohun méje ti Ẹ̀mí Mímọ́ yóò ṣe nínú rẹ
- Àwọn ohun méjì ti Ẹ̀mí Mímọ́ yóò ṣe fún ọ
- Nígbà tí Ọlọ́run ba sàbẹ̀wò sí ọ
- Bi a ti ṣelè gba ìyanu àti múdání
- Nisisiyi ti o ti di Àtúnbí
- Ìwọ àti Ẹ̀mí Mímọ́
- Kò sí ọ̀kan nínú àwọn àrùn wọ̀nyìí
- Òróró àti Àṣọ ìléwọ́
- Ètò rẹ nínú Kristi
- Títọ́jú Ìwòsàn rẹ mo
- Ilẹ̀ Ìlérí
- Ìyípadà ayé rẹ
- Ìwé Bíbélì Kíka ojojúmọ́ Rhapsody ti Realities
- Gbígbà ipa ọ̀nà òòrun Rhapsody ti Realities *(*w3 62, 3 & 4)*
- Ìwòsàn láti ọ̀run ***(*w3 1, 2 & 3)***
- Báwo ni a ti ṣe le gbàdúrà